# A SỌ ASỌTẸLẸ IJIYA JUDA

**Isaiah 5:1-30**

**ẸKỌ 349 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Nwọn o si wọ̀ inu ihò apata lọ, ati inu ihò ilẹ, nitori ibẹru OLUWA, ati nitori ogo ọlanla rẹ̀, nigba ti o ba dide lati mì ilẹ aiye kijikiji" (Isaiah 2:19).**

**I Ọgba Ajara Oluwa**

1 A gbin ọgba-ajara Oluwa si ori oke ẹlẹtù-loju, a si fi ifẹ ati ikẹ tọju rẹ, Isaiah 5:1, 2; Orin Dafidi 80:8, 9, 15

2 Oluwa wò pé ki o so eso, ṣugbọn eso kikan ni o so, Isaiah 5:3, 4; Jeremiah 2:21

3 Oluwa paṣẹ pe ki a fi ọgba naa ṣòfo, Isaiah 5:5, 6; Orin Dafidi 80:12, 13

4 Ọgba-ajara Oluwa yii ni ile Israẹli, Juda si ni igi-gbigbìn ti o wu ni, Isaiah 5:7

**II Isọdahoro awọn Eniyan Buburu**

1 A sọ pe ègbé ati òṣi yoo jẹ ti awọn olojukokoro, Isaiah 5:8-10; Ẹksodu 20:17; Habakkuku 2:9; Luku 12:15; Kolosse 3:5

2 Iwà imutipara wá si idajọ niwaju Ọlọrun, Isaiah 5:11-13, 22, 23; Lefitiku 10:9; Owe 20:1; 23:29-31; Luku 21:34; Romu 13:13

3 Ọrun-apaadi ti la ẹnu rẹ̀ lai ni iwọn lati gba awọn eniyan buburu, Isaiah 5:14

4 Awọn oniṣẹ buburu ati agberaga ni a mu wá sinu idajọ, Isaiah 5:15, 17-21; Owe 16:18; 21:4; Luku 1:52; 1 Johannu 2:16; Malaki 4:1

**III Idajọ Ọlọrun**

1 Oluwa awọn ọmọ-ogun ni a o gbega ni idajọ, Isaiah 5:16; Ifihan 20:11-15

2 Ọlọrun ni ẹtọ gidigidi lati dá awọn Ọmọ Israẹli lẹjọ, Isaiah 5:24, 25

3 Ọlọrun lo awọn orilẹ-ede ti o wà lọna jijin réré gẹgẹ bi ohun-elo lati fi ṣe idajọ, Isaiah 5:26-30

## ALAYE

"Emi pè ọrun ati ilẹ jẹri ti nyin li oni pe, emi fi iye ati ikú, ibukún ati egún siwaju rẹ: nitorina yàn iyè, ki iwọ ki o le yè, iwọ ati irú ọmọ rẹ" (Deuteronomi 30:19). Awọn Ọmọ Israẹli ni Oluwa rán iṣẹ yii si; ṣugbọn nitori pe Jesu jẹ Ọdọ-Agutan "ti a ti pa lati ipilẹṣẹ aiye" wá, gbogbo eniyan ti o wà ninu ayé ni a rán iṣẹ naa si. Ọna si Ọrun ṣi silẹ fun gbogbo eniyan. Gẹgẹ bi o ti jẹ ohun aigbọdọ ma ṣe fun olukuluku Ọmọ Israẹli lati yàn lati sin Ọlọrun tabi lati má sin In, bakan naa ni olukuluku eniyan ni lati pinnu fun ara rẹ lati yan ọna iye ainipẹkun tabi ikú ainipẹkun. Ẹnikẹni ti o ba fẹ lati gbé ni ayeraye pẹlu Ọlọrun ni Ọrun ni lati wá igbala Ọlọrun ki o si maa gbé gẹgẹ bi Ọrọ Ọlọrun nigba ti o wà ninu ayé. Nitori naa ipa ti ẹni kọọkan bá yàn ni yoo sọ ipin rẹ̀ ni ayeraye.

### Ọgba Ajara Oluwa

"Nisisiyi, emi o kọ orin si olufẹ ọwọ́n mi, orin olùfẹ mi ọwọ́n niti ọ̀gba àjara rẹ̀. Olufẹ ọwọ́n mi ni ọ̀gba àjara lori okè ẹlẹtù loju" (Isaiah 5:1). Ori okè ẹlẹtù loju yii naa ki i ṣe ibomiran bi kò ṣe Kenaani, Ilẹ Ileri ti a fi fun awọn ọmọ Israẹli ẹrú ti Ọlọrun da silẹ kuro ninu ajaga lile buburu ti awọn ara Egipti. Awọn okuta ilẹ naa, ti i ṣe awọn ẹya keferi abọriṣa ni ilẹ Kenaani ki awọn Ọmọ Israẹli to de, ni a lé kuro nipa agbára Ọlọrun nigba ti awọn Ọmọ Israẹli gba ini wọn. Bi keferi kan ba kù silẹ si ilẹ naa ti Ọlọrun fi fun Israẹli, o wà nibẹ nitori pe awọn Ọmọ Israẹli kuna lati ṣe ati lati pa gbogbo aṣẹ Ọlọrun mọ́.

Oluwa fi Otitọ sagbara yi ọgba ajara Rẹ̀ ká lati lé awọn orilẹ-ède keferi sẹyin ki wọn ma ba ba awọn irugbin Rẹ̀ titun jẹ́. "Yio si ṣe, bi iwọ ba farabalẹ gbọ́ ohùn OLUWA Ọlọrun rẹ, lati ma kiyesi ati ṣe aṣẹ rẹ̀ gbogbo ti mo pa fun ọ li oni, njẹ OLUWA Ọlọrun rẹ yio gbé ọ ga jù gbogbo orilẹ-ède aiye lọ … OLUWA

yio mu awọn ọtá rẹ ti o dide si ọ di ẹni ikọlù niwaju rẹ: nwọn o jade si ọ li ọ̀na kan, nwọn o si sá niwaju rẹ li ọ̀na meje" (Deuteronomi 28:1, 7).

A kọ́ ile ẹṣọ kan saarin ọgba ajara Oluwa. A kọ́ awọn ile-iṣọ igbaani fun ibi aabo ati isasi nigba ogun ati ewu. A kọ́ wọn ga to bẹẹ gẹ ti awọn oluṣọ ti o wa ni tente ori ile-iṣọ naa le maa ri bi ọta ba n bọ̀. Awọn ile-iṣọ naa lagbara o si nipọn to lati le ọtá sẹyin bi o ba fẹ gbiyanju lati bá ẹni ti o ni ọgba ajara naa jà. Ilu Jerusalẹmu ati Tẹmpili Oluwa di ibi aabo nla fun awọn Ọmọ Israẹli, pataki ni akoko igba ti wọn ba n sin Oluwa pẹlu gbogbo ọkàn, iye ati agbára wọn. (Ka Isaiah 37:14-23, 33-36).

Oluwa wi fun ile Israẹli pe awọn ni ọgba-ajara Oun – ati pe awọn ọkunrin Juda jẹ́ aṣayan ọgbin Ọlọrun. Oluwa ni ẹtọ lati reti ọ̀pọ ikore lati inu laalaa Rẹ̀; bi o ba si ṣe pe awọn Ọmọ Israẹli ti fi otitọ ọkàn sin Ọlọrun ni, ireti i ba wa fun iru ikore bẹẹ. "Awọn ẹniti a gbin ni ile OLUWA, yio gbà ni agbala Ọlọrun wa. Wọn o ma so eso sibẹ ninu ogbó wọn" (Orin Dafidi 92:13, 14). Kò si aleebu kankan lara ọgbin Ọlọrun. "Emi ti gbin ọ ni ajara ọlọla, irugbin rere patapata."

**Orin Idajọ**

"Eeṣe ti iwọ fi yipada di ẹka ajara ajeji si mi?" (Jeremiah 2:21). Orin idajọ Isaiah fi hàn pé Oluwa ti ṣe ohun gbogbo ti o yẹ ni ṣiṣe lati mu ki ọgba ajara Rẹ̀ jẹ́ eleso; ṣugbọn nigba ti O n reti ikore, eso kikan ni ọgba ajara Rẹ̀ n so. Gbogbo awọn Ọmọ Israẹli ni apapọ, kọ̀ lati sin Ọlọrun. O dabi ẹni pe wọn yàn lati fi ara fun ẹ̀ṣẹ ati ibọriṣa ki wọn si wa doju kọ ibinu ati idajọ Ọlọrun oloootọ. Awọn Ọmọ Israẹli mọ̀ pe Ọrun n duro de awọn wọnni ti o fi ọkàn otitọ sin Ọlọrun ni ayé, wọn si mọ̀ pẹlu pé ọrun apaadi ti kò ṣe e yẹ silẹ ni opin igbesi-ayé ẹ̀ṣẹ ati aiṣododo; sibẹ awọn ti o pọju ninu awọn Ọmọ Israẹli yàn lati wà ninu ẹ̀ṣẹ si i. Njẹ a le rò wi pe yiyan were kan tun wà ti o ga ju eyi lọ?

Ki ni a ba ṣe si ọgba-ajara alaileso naa? Oluwa sọtẹlẹ pe Oun yoo mu ọgba aabo rẹ̀ kuro, a o si jẹ ọgba-ajara naa run – a o si wó ogiri rẹ̀ lulẹ, a o si tẹ ogba-ajara naa mọ́lẹ̀. A gba ibukun Oluwa ti o wà lori Israẹli kuro ati lai pẹ a tú wọn ká si origun mẹrẹẹrin ayé. Oluwa dá ọ̀jo duro lori ilẹ naa, lai pẹ ilẹ daradara naa di aṣálẹ̀ gbigbẹ. Aṣayan ọgbin Oluwa ti o wà lori okè ẹlẹtù loju di igi gbigbẹ patapata; iba ma ṣe aanu ati majẹmu Oluwa, awọn Ọmọ Israẹli i ba ti parẹ lori ilẹ ayé. Lati ẹnu wolii yii, Ọlọrun sọ diẹ ninu awọn ẹ̀ṣẹ ti awọn Ọmọ Israẹli jẹbi rẹ̀, awọn ọlọfintoto paapaa yoo gbà pe Ọlọrun ni idi lati rán idajọ gbigbona sori awọn alaiwa-bi-Ọlọrun yii.

**Iyi Igbà Pada**

Aworan ọ̀rọ ti wolii Isaiah n fi han ni ni akoko yii nipa awọn Ọmọ Israẹli jẹ́ eyi ti kò fani mọra ni kikà tabi ni gbigbọ́. Adura wa ni pe ki Ọlọrun le jẹ ki idajọ kan ṣoṣo yii lori ẹ̀ṣẹ tó lati kilọ fun gbogbo ẹlẹṣẹ lati sá kuro ninu ibinu Olodumare ki wọn si yi pada tọkantọkan lati sin Ọlọrun alaaye ati otitọ.

Fi awọn Keferi rọpo awọn Ọmọ Israẹli ninu aworan ọrọ yii, a o ri i pe bakan naa ni ohun ti n ṣẹlẹ lọjọ oni rí. Nigba ayé oore-ọfẹ, awọn Keferi gan an ni Ọlọrun rán Ẹmi Rẹ̀ si. Oluwa ti pese gbogbo anfaani fun igbala gbogbo eniyan, ṣugbọn Ọlọrun fun eniyan ni ominira lati le yan ohun ti o ba fẹ, i baa ṣe iye ainipẹkun tabi ikú ayeraye. Ọlọrun ti ṣe ohun gbogbo ti o wà ni ipa Rẹ̀ lati mú ọmọ-eniyan wá si ironupiwada; ṣugbọn ni apapọ wọn n kọ eti didi si ipe aanu Rẹ̀ sibẹ. Idajọ ti Oluwa sọ nipa ọlọtẹ Israẹli yoo wá sori awọn Keferi ti wọn kọ̀ lati ronu piwada ẹ̀ṣẹ wọn ati lati gba oore-ọfẹ Ọlọrun si ookan-aya wọn.

**Imọ-ti-ara-ẹni-nikan**

Oluwa fi awọn olojukòkoro Israẹli ré, sibẹ idajọ ẹ̀ṣẹ Israẹli kò mú ẹ̀ṣẹ naa kuro ninu ayé. Awọn eniyan ṣi jẹ́ olojukokoro sibẹ, bi ibinu Ọlọrun ṣe muna nigba nì, bẹẹni o ṣi muna titi di oni nitori ẹ̀ṣẹ yii. Jesu wi fun awọn olugbọ Rẹ̀ pe: "Kiyesara ki ẹ si mã ṣọra nitori ojukòkoro: nitori igbesi aiye enia ki iduro nipa ọ̀pọ ohun ti o ni" (Luku 12:15). Ọpọ ohun ti eniyan ni tabi ohun ti o ṣe, ni ayé fi maa n diwọn aṣeyọri ti eniyan ni, ṣugbọn Ọlọrun n diwọn aṣeyọri eniyan nipa ọ̀pọ ohun ti ẹmi ti o ni ati ibi ti o dé nipa ti ẹmi. Iyatọ pupọ ni o wa laaarin idiwọn mejeeji.

Ẹṣẹ imọ-ti-ara-ẹni-nikan miran ti Oluwa tun n dá-lẹbi lọjọ oni, gẹgẹ bi o ti ṣe ni akoko awọn Ọmọ Israẹli ni ẹ̀ṣẹ imutipara. Iwe iṣiro fi han ni pe ọkẹ aimoye ẹgbẹgbẹrun naira ni awọn eniyan n ná

lọdọọdun lori ohun oloro yii, awọn ẹni ti kò tilẹ yẹ, nipa aini, lati le fi ara wọn fun ayé ijẹkujẹ, ailere ati ibajẹ ti ohun oloro yii n mu wá. Ọpọ agbo ile ati awọn ọmọ wẹwẹ ni a n dù ni ounjẹ oojọ ati anfaani fun igbesi ayé wọn nitori pe ọ̀kan ninu awọn obi wọn tabi awọn mejeeji ti ná gbogbo owó tán lori ọti ati awon ohun ibajẹ miiran gbogbo. Ni ilu Amẹrika, eniyan bi aadọjọ ọkẹ ni ọti mimu ti di baraku fun, ti wọn kò tun le fi ọti silẹ mọ́. Ọkẹ aimoye awọn miiran ni wọn n mu ọti gbajumọ, ti ọti mimu n ti si jamba ti n ṣe ikú pa ọ̀pọlọpọ eniyan ni opopo ọ̀na wa. Ọrọ Ọlọrun ti ki i tase, sọ ipin awọn ọmuti: "Ipania, imọtipara, iréde oru ati iru wọnni: awọn ohun ti mo nwi fun nyin tẹlẹ, gẹgẹ bi mo ti wi fun nyin tẹlẹ ri pe, awọn ti nṣe nkan bawọnnì ki yio jogún ijọba Ọlọrun" (Galatia 5:21).

**Ọrun Apaadi di Gbigbooro**

Iwa awọn eniyan buru jai, o si gbilẹ to bẹẹ gẹẹ ti Ọlọrun fi wi fun wolii naa pe, "Ipò-okú ti fun ara rẹ̀ li àye, o si là ẹnu rẹ̀ li aini iwọn: ati ogo wọn, ati ọ̀pọlọpọ wọn, ati ọṣọ́ wọn, ati awọn ẹniti nyọ̀, yio sọkalẹ lọ sinu rẹ̀" (Isaiah 5:14). Ki i ṣe eniyan ni a dá ọrun apaadi fun tẹlẹtẹlẹ, ṣugbọn a pese rẹ silẹ fun "Eṣu ati fun awọn angẹli rẹ̀" (Matteu 25:41). A maa n fi ṣe ọ̀rọ sọ pe ẹni ti o ba n gbé igbesi-ayé èṣu yoo fara mọ́ owo ọ̀ya èṣu. "Ikú li ère ẹ̀ṣẹ" (Romu 6:23). "Awọn ojo, ati alaigbagbọ́, ati ẹni irira, ati apania, ati àgbèrè, ati oṣó, ati abọriṣa, ati awọn eke gbogbo, ni yio ni ipa ti wọn ninu adagun ti nfi iná ati sulfuru jò; eyi ti iṣe ikú keji" (Ifihan 21:8).

Iwa ẹṣẹ kan naa ti awọn Ọmọ Israẹli n hù nigbaanì ni awọn eniyan ayé ode-oni n hù. Bi Ọlọrun ti dá ẹ̀ṣẹ Israẹli lẹjọ, bẹẹ gẹgẹ ni yoo ṣe idajọ ẹ̀ṣẹ ni ọkàn ati igbesi-ayé olukuluku Keferi. "Bayi li emi o ṣe si ọ, iwọ Israẹli: ati nitoriti emi o ṣe eyi si ọ, mura lati pade Ọlọrun rẹ" (Amosi 4:12). Ọlọrun tun n sọ fun gbogbo eniyan pe: "Yàn iye, ki iwọ ki o le yè, iwọ ati irú-ọmọ rẹ" (Deuteronomi 30:19).

**AWỌN IBEERE**

1 Ta ni Ọgba-ajara Oluwa?

2 Ọna wo ni Oluwa gbà daabo bo ọgba-ajara Rẹ̀?

3 Ki ni a le fi wé ile-iṣọ ti wolii naa ṣe apejuwe rẹ̀?

4 Ki ni Oluwa ri nigba ti O n reti eso ninu ọgba-ajara Rẹ̀?

5 Ki ni ṣẹlẹ si ọgba-ajara Oluwa? Ki ni ṣe?

6 Ọna wo ni a gba jẹ ojukokoro awọn Ọmọ Israẹli niya?

7 Ki ni Oluwa sọ nipa imutipara?

8 Ki ni ṣe ti ipò-okú fi fun ara rẹ̀ ni àyè?